# ẸYA-ARA TI A KÒ LÈ TÙ LOJU

**Jakọbu 1:26; 3:1-18**

**ẸKỌ 359 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ninu ọ̀rọ pipọ, a kò le ifẹ ẹ̀ṣẹ kù: ṣugbọn ẹniti o fi ète mọ ète li o gbọ́n" (Owe 10:19).**

**I Orisun Kikoro**

1 Ahọ́n eniyan ti a kò ṣe akoso rẹ̀ jẹ́ ohun ti o buru lọpọlọpọ, Jakọbu 1:26; 3:1-6; Orin Dafidi 140:3; Romu 3:13

2 Oniruuru ọ̀rọ buburu gbogbo ni Ọrọ Ọlọrun dá lẹjọ, Jakọbu 3:7-12, 14-16

(a) Isọrọ-ẹni-lẹyin, Orin Dafidi 15:1-3; 50:19-23; 101:5; Jeremiah 9:3-5, 8; Romu 1:30; 2 Kọrinti 12:20

(b) Ọrọ asán, Jobu 11:2; 15:3; Owe 29:11; Oniwasu 5:3; 10:12-14; Titu 1:10

(d) Ofofo, Lefitiku 19:16; Owe 17:9; 18:8; 20:19; 26:20; Romu 1:29

(e) Ifunnu, Jakọbu 3:5; Owe 27:1, 2; Matteu 6:2; Romu 1:30; II Timoteu 3:2

3 Ọlọrun yoo pa awọn ti o n sọrọ buburu run, yoo si yi ètekéte wọn sori ara wọn, 2 Peteru 2:10-12; Juda 8-10, 14-16; Ifihan 21:8; Orin Dafidi 7:15, 16; 57:4-6; 64:1-9

**II Orisun Didùn**

1 Lati oke Ọrun wá ni gbogbo ọ̀rọ Onigbagbọ́, wọn a si maa gbé eniyan ró, Jakọbu 3:13, 17, 18; Orin Dafidi 15:3; Owe 31:26; Efesu 4:29; Kolosse 4:6; Titu 2:8; 3:2; 1 Peteru 3:10, 11; Ifihan 14:5

## ALAYE

### A Dá Isọrọ-Buburu Lẹbi

"Ẹnyin ọmọ paramọlẹ, ẹnyin ti iṣe enia buburu yio ti ṣe le sọ̀rọ rere? nitori ninu ọ̀pọlọpọ ohun inu li ẹnu isọ. Enia rere lati inu iṣura rere ọkàn rẹ̀ ni imu ohun rere jade wá: ati enia buburu lati inu iṣura buburu ni imu ohun buburu jade wá. Ṣugbọn mo wi fun nyin, gbogbo ọ̀rọ wère ti enia nsọ, nwọn o jihin rẹ̀ li ọjọ idajọ. Nitori nipa ọ̀rọ rẹ li a o fi da ọ lare, nipa ọ̀rọ rẹ li a o si fi da ọ lẹbi" (Matteu 12:34-37).

Pẹlu iru gbolohun ọ̀rọ bayii ni Ọrọ Ọlọrun dá gbogbo isọkusọ lẹbi lai dá eyikeyi si. Gẹgẹ bi odò ti n ṣàn ni ahọ́n ọkàn ti a kò tunbi n tú ẹ̀ṣẹ dà sinu ayé. Otitọ ọ̀rọ gidi ni pe, gbogbo ọ̀rọ ẹnu wa lati ọjọ de ọjọ yoo pada wa dá wa lare tabi dá wa lẹbi titi ayeraye niwaju Ọlọrun! (Ka Juda 8, 10, 14-16).

Iru awọn ẹsẹ Iwe Mimọ bawọnyii kọ́ wa pe isọrọ-buburu maa n rin pọ̀ pẹlu iṣọtẹ si Ọlọrun ati eto iṣakoso Rẹ̀. Siwaju si i, gbogbo awọn ti o ba n sọrọ buburu ni yoo gba iru idajọ gbigbona kan naa ti a ṣe fun awọn ọlọtẹ si Ijọba Ọlọrun. Bi Ọlọrun kò ba gba awọn angẹli layè lati sun Satani, olori ọta eniyan lẹsun pẹlu ẹgan, wo o nigba naa bi eniyan ṣe gbọdọ kiyesara gidigidi ki wọn máṣe yara sọrọ tabi lati maa sọrọ buburu si ẹnikẹni tabi nipa ẹnikẹni.

Ni titẹle ẹkọ Ọrọ Ọlọrun, Paulu tọrọ aforiji lọwọ olori alufaa ẹni ti oun kò tilẹ mọ̀ pe olori alufaa ni i ṣe, bi o tilẹ dabi ẹni pe o ni ẹtọ lati sọrọ nipa rẹ̀ bẹẹ. (Ka Iṣe Awọn Apọsteli 23:2-5; Ẹksodu 22:28; Oniwasu 10:20).

### Ahọ́n Oloro

Ọ̀kan ninu awọn ohun ija eṣu ti o muna ju lọ ni sisọ isọkusọ nipa ẹlomiran. Satani ni "olufisùn" awọn arakunrin (Ifihan 12:10); eṣu ni o n ti ẹnikẹni nigba ti o ba n tẹnu mọ awọn ohun buburu nipa ẹlomiran bi o tilẹ jẹ pe otitọ ni wọn i ṣe.

Iṣẹ́ ti Onigbagbọ́ yatọ si wi pe ki o maa ro aṣiṣe arakunrin kan kaakiri; tabi ẹ̀ṣẹ rẹ̀ paapaa, bi o ba tilẹ ṣe pe o ti dẹṣẹ. Ọrọ Ọlọrun sọ wi pe: "Ará, bi a tilẹ mu enia ninu iṣubu kan, ki ẹnyin ti iṣe ti ẹmi ki o mu iru ẹni bẹ̃ bọ̀ sipò ni ẹmi iwa tutu; ki iwọ tikararẹ mã kiyesara, ki a má ba dan iwọ nã wò pẹlu. Ẹ mã ru ẹrù ọmọnikeji nyin, ki ẹ si fi bẹ̃ mu ofin Kristi ṣẹ" (Galatia 6:1, 2). Ko ṣe e ṣe ki eniyan ṣi iru gbolohun ọ̀rọ yii tumọ ki o si pe e ni aṣẹ fun ẹnikẹni lati maa ṣofófó tabi sọrọ isọkusọ nipa aiṣedeedee tabi ẹ̀ṣẹ ẹlomiran. Iṣẹ́ eṣu ni lati pa ọkan eniyan run; lati maa sọrọ nipa igbesi-ayé awọn eniyan ti kò le gbeniro, ti kò si jẹ fun ogo Ọlọrun, eyi jẹ́ riran iṣẹ́ eṣu lọwọ.

“Ẹniti nṣofofo fi ọ̀ran ipamọ́ hàn; ṣugbọn ẹniti nṣe olõtọ-ọkàn a pa ọ̀rọ na mọ́” (Owe 11:13). Siwaju si i, “Alayidayida enia dá ija silẹ: asọ̀rọkẹlẹ ya awọn ọrẹ́ ni ipa” (Owe 16:28). Awọn wọnyii jẹ diẹ ninu ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun ti a le tọka si nipa fifi arakan sọrọ buburu nipa eniyan. Abajọ ti Jakọbu nipa imisi Ẹmi Mimọ fi tẹnu mọ otitọ ni,pe, “Iná si ni ahọ́n, aiye ẹ̀ṣẹ si ni: li arin awọn ẹ̀ya ara wa li ahọn ti mba gbogbo ara jẹ́ ti o si ntinabọ ipa aiye wa; ọrun apadi si ntinabọ on na” (Jakọbu 3:6).

**Ifunnu**

Ifunnu paapaa jẹ́ ohun buburu kan ninu ahọ́n eniyan ti a le fi si àye kan naa pẹlu ọ̀rọ asán, iṣofofo ati isọrọ-ẹni-lẹyin. Bibeli sọ pe: “Ẹniti nsọ ti ara rẹ̀ nwa ogo ara rẹ̀: ṣugbọn ẹniti nwa ogo ẹniti o rán a on li olõtọ, kò si si aiṣododo ninu rẹ̀” (Johannu 7:18). Igberaga jẹ́ ẹ̀ṣẹ ti i maa tabuku bá eniyan, iyin-ara-ẹni jẹ́ eso igberaga. Eredi yiyìn ara ẹni kò ju pe ki awọn eniyan le fi oju ẹni nla wo ni, lati gbé ni ga ati lati fun ni ni ipo ọlá. Ni ọ̀pọlọpọ igba ni a n ri i pe awọn afunnu ki i ni ohun ti wọn n pariwo rẹ̀ pe awọn ni, idi rẹ̀ ti wọn si fi n funnu ni yii. Ninu ijagun Onigbagbọ́, ifunnu kan wa ti o tọ́ ti o si yẹ. Onipsalmu sọ pe, “Ọkàn mi yio ma ṣogo rẹ̀ niti OLUWA: awọn onirẹlẹ yio gbọ́, inu wọn yio si ma dùn” (Orin Dafidi 34:2). Onigbagbọ́ le ṣogo pupọ nipa Olurapada rẹ̀ Nla, ati nipa iṣẹ́ agbára Rẹ̀ nla si awọn ọmọ eniyan. Ṣugbọn ifunnu nipa ti ara, ẹ̀ṣẹ ni!

**Orukọ OLUWA**

Aabo wà fun Onigbagbọ́ lati bọ́ kuro ninu iwa aile-fi-ete-mọ́-ete. Ọlọrun ti ṣe ileri lati dá awọn eniyan Rẹ lare kuro ninu gbogbo ẹ̀sun eke ti eṣu le fi wọn sùn. Ọrọ Ọlọrun sọ bayii pe: “Orukọ OLUWA, ile-iṣọ agbara ni: olododo sá wọ inu rẹ̀, o si là” (Owe 18:10). Olododo le sá lọ sọdọ Ọlọrun, aabo Rẹ̀, yoo si pa wọn mọ́ kuro ninu wahala gbogbo, ati ti ibajẹ ahọ́n ẹ̀tan.

Kika Orin Dafidi ori ikẹrinlelọgọta kọ́ wa lẹkọọ nipa ète awọn eniyan buburu ati iṣẹgun Ọlọrun lori wọn. “Ẹniti npọ́n ahọn wọn bi ẹnipe idà, ti nwọn si fa ọrun wọn le lati tafa wọn, ani ọ̀rọ kikoro: ki nwọn ki o le ma tafà ni ikọkọ si awọn ti o pé: lojiji ni nwọn tafa si i, nwọn ko si bẹ̀ru”. Ki ni aabo awọn olododo ni irú akoko bayii? “Ṣugbọn Ọlọrun yio tafa si wọn (awọn eniyan buburu) lojiji; nwọn o si gbọgbẹ. Bẽni ahọn wọn yio mu wọn ṣubu lu ara wọn: gbogbo ẹniti o ri wọn yio mi ori wọn” (Orin Dafidi 64:3, 4, 7, 8).

Hamani, ẹni ti o ri ojurere ọba, ṣe ilara Mọrdekai, o si rò ninu ọkàn rẹ̀ lati ṣe e ni ibi. O fi ọgbọn ẹ̀wẹ́ ṣe eto igbega fun ara rẹ̀, ati iparun fun Mordekai. Oluwa sọ imọ̀ rẹ̀ di asán, ohun naa gan an ti o ti gberò lati ṣe si Mọrdekai si pada sori oun tikara rẹ̀. Ọla ti oun ti pinnu fun ara rẹ pada di ti Mọrdekai (Wo Ẹsteri 7:10). Bayii ni Ọlọrun maa n mú ahọ́n awọn eniyan buburu pada sori ara awọn tikara wọn ti O si maa n fi iwa ika wọn pa wọn run.

Laaarin iran ti o ti kọja, o ti jẹ ohun iṣogo fun awọn anikan-paṣẹ lori ilu pe bi a ba n pa irọ kan naa nigba gbogbo ti a si n tẹnumọ ọn, nigba ti o ba ṣe, ayé yoo gba irọ́ naa si otitọ. Ayé paapaa gba ọ̀rọ yii si otitọ pe nigba ti irọ ti yi ayé po de idaji, n ṣe ni otitọ “Ṣẹ̀ṣẹ n kó bata si ẹsẹ̀.” Awọn eniyan nipa ti ara le gba iru awọn gbolohun ọ̀rọ wọnyii si otitọ, ṣugbọn aiṣootọ kò le tẹ ododo rì. Bẹẹ gẹgẹ ni kò si eyikeyi ninu iwà ibi ti o le pa otitọ run. Jesu Kristi sọ pe, “Emi li ọ̀na, ati otitọ ati iye” (Johannu 14:6). Kò si irọ ti eṣu ti i pa ri, tabi ti yoo ṣẹṣẹ pa ti o le yi Ọmọ Ọlọrun tabi Otitọ Ọlọrun pada rara. Otitọ ti Ọdọ Ọlọrun wá; bẹẹ si ni otitọ, ohunkohun ti o wu ki o duro le lori, kò ṣe i yà nipa pẹlu Ọlọrun, nitori pe Oun ni i ṣe orisun ohun gbogbo ti iṣe rere ati titọ.

Gbogbo ibi ati isọrọ buburu ti ọdọ Satani wá. Jesu sọ fun awọn ti wọn n ṣe atako Ọrọ Rẹ̀ pe: “Ti eṣu baba nyin li ẹnyin iṣe, ifẹkufẹ baba nyin li ẹ si nfẹ ṣe. Apania li on iṣe lati atetekọṣe, ko si duro ni otitọ; nitoriti ko si otitọ ninu rẹ̀. Nigbati o ba nṣeke, ninu ohun tirẹ̀ li o nsọ, nitori eke ni,ati baba eke” (Johannu 8:44). Nitori naa, lati pa irọ tabi ṣe aiṣootọ lọnakọna fi hàn pe irú ẹni bẹẹ n ṣiṣẹ fun eṣu. Ọlọrun kò le fara da aiṣootọ, awọn eke ki yoo si ni ipin ni Ijọba Ọlọrun. “Ohun alaimọ́ kan ki yio si wọ inu rẹ̀ rara, tabi ohun ti nṣiṣẹ irira ati eke; bikoṣe awọn ti a kọ sinu iwe iye Ọdọ Agutan.” “Nitori li ode ni awọn ajá gbé wà, ati awọn oṣó, ati awọn àgbere, ati awọn apania, ati awọn abọriṣa, ati olukuluku ẹniti o fẹran eke ti o si nhuwa eke” (Ifihan 21:27; 22:15).

Ọkàn Onigbagbọ́ kún fun ọsọ rere ti i ṣe ti Oluwa, yoo si maa sọrọ lọna ti yoo fi wu Oluwa rẹ̀. “Ọgbọ́n ti o ti oke wá, a kọ́ mọ́, a si ni alafia, a ni ipamọra, ki si iṣoro lati bẹ̀, a kún fun ãnu ati fun eso rere, li aisi ègbè, ati laisi agabagebe. Eso ododo li a ngbìn li alafia fun awọn ti nṣiṣẹ alafia” (Jakọbu 3:17, 18).

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni mú ki ahọ́n jẹ́ alaigbọran ẹya ara?

2 Ki ni ṣe ti Bibeli fi sọ pe a sọ ahọ́n si ina ọrun apaadi?

3 Ta ni i ṣe baba eke ati isọrọ buburu gbogbo?

4 Ki ni yoo ṣẹlẹ si gbogbo awọn ti n sọrọ ibi?

5 Bawo ni o ṣe yẹ ki Onigbagbọ́ maa sọrọ?

6 Ki ni ṣe ti Onigbagbọ́ kò gbọdọ dá si ọ̀rọ ofofo?

7 Ta ni i ṣe olufisun awọn arakunrin?

8 Aabo wo ni Onigbagbọ́ ni lati le bọ́ lọwọ isọkusọ ati ifi ọrọ kẹlẹ banijẹ?